# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**OṢÙ KÍNNÍ, ỌDÚN 2024**

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

## OṢÙ KÍNNÍ, ỌDÚN 2024 – PÀṢẸ FÚN ỌDÚN

**1. Ọkàn mi yin Ọba ọ̀run,**
Mú ọrẹ wá sọ́dọ̀ Rẹ,
'Wọ ta wòsàn, t'a dáríjì
Tal'ába ha yìn bí Rẹ?
Yín Olúwa, Yín Olúwa,
Yín Ọba àìnípẹ̀kun.

2. Yín fún ànú t'ó ti fi hàn
F'áwọn Bàbá 'nú pọnjú
Yín Ì Ọ̀kan ná nì títí
Ó lọ́ra láti bínú
Yín Olúwa, Yín Olúwa,
Ológo n'nú òtítọ́.

3. Bí Bàbá ni Ó ntọ́jú wa
Ó sì mọ àìlera wa;
Jẹ́jẹ́ l'ó ngbé wa lápá Rẹ̀
Ó gbà wá lọ́wọ́ ọ̀tá
Yín Olúwa, Yín Olúwa
Ànú Rẹ̀, yí ayé ká.

4. Ángẹ́l, ẹ jùmọ̀ bá wa bọ
Ẹ̀yin nri lójúkojú
Òrùn, Oṣùpá, ẹ wólẹ̀
Àti gbogbo àgbáyé
Ẹ bá wa yìn, Ẹ bá wa yìn
Ọlọ́run Olótìtọ́

**1. Ọlọ́run t'ọdún t'ó kọjá**

Ìrèt'èyí tí mbọ;
Ib'isádi wà ní iji
À t'ilé wà láíláí.

2. L'ábẹ́ òjìjì ìtẹ́ Rẹ
L'áwọn èyàn Rẹ ngbé
Tító l'ápá Rẹ̀ nìkanṣo
Àbò wa sì dájú.

3. K'áwọn òkè k'ó tó dúró
Tàbí k'a tó d'áíyé
Láíláí Ìwọ ni Ọlọ́run
Bákanná, l'áìlópin!

4. Ẹgbẹ̀rún ọ̀dun l'ójú Rẹ
Bí alẹ́ kan l'ó rí
B'íṣọ̀ kan, l'áfẹ̀mọ́júmọ́
Kí òrùn k'ó tó là

5. Ọ̀jọ̀ wa bí òdò ṣíṣán,
Ọ̀pọ̀ l'ó sì ngbé lọ;
Wọ́n nlọ, wọ́n di ẹni 'gbàgbé
Bí àlá tí a nrọ.

6. Ọlọ́run t'ọdún t'ó kọjá
Ìrèt'èyí tí mbọ̀
Má ṣ'àbò wá 'gbà 'yọnu dé
À t'ìlé wá láíláí.

## ỌRỌ̀ AGBÁRA

1. Gbogbo ìfẹ́, èrò àti àwọn ètò ọ̀tá, tó lòdì sí ìtẹ̀síwájú mi l'ọ́dún yìí kò ní dúró, bẹ́nì wọn kò ní wá sí ìmúṣẹ, ní orúkọ Jésù.
2. Agbára ìyówù, tí wọ́n yàn láti ti ilẹ̀kùn mi l'ọ́dún yìí, Ọlọ́run Èlíjàh yóò pa ọ́ run lónìí, ní orúkọ Jésù.
3. Ibi ìyówù tí mo bá lọ l'ọ́dún yìí, èmi kòní ní ìrírí àjálù tàbí ijàmbá, ní orúkọ Jésù.
4. L'ọ́dún yìí, kòsí agbára òkùnkùn tí yóò lè dá ìyára kánkán mi atòkèwá dúró, ní orúkọ Jésù.
5. Nípa àánú Rẹ, Ọlọ́run Ábráhámù, Ìsáákì àti Jákọ́bù, fi ayé mi dójúti ìjọba òkùnkùn, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo ìdíwọ́ àti ìdènà ìkọ̀kọ̀ sí ìtẹ̀síwájú mi l'ọ́dún yìí yóò gba ìparun lónìí, ní orúkọ Jésù.
7. Agbára fún àwọn ilẹ̀kùn tó ṣí sílẹ̀ àti ìyára kánkán atòkèwá l'ọ́dún yìí, ayé mi ṣí sílẹ̀ fún ọ, gbé mi wọ̀ báyìí, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ – ÌJẸ́WỌ́: ORIN DÁFÍDÌ 91

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Mo múso gbogbo pámpẹ́ òkùnkùn tí wọ́n dẹ fún mi l'ọ́dún yìí, ní orúkọ Jésù.

4. L'ọ́dún yìí, Jèhófà yóò dìde nínú ìbínú Rẹ̀, yóò sì jà fún mi, ní orúkọ Jésù.
5. Èmi kòní wọ aṣọ ibànújẹ́ l´ọ́dún yìí, ní orúkọ Jésù.
6. Agbára ìyówù, tí wọ́n yàn láti pa mí l'ọ́dún yìí, yóò pa ara rẹ̀, yóò sì kú, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo pẹpẹ búburú tí wọ́n gbé dìde lòdì sí mi l'ọ́dún yìí yóò wó lulẹ̀, ní orúkọ Jésù.

---

## ÀDÓ Ọ̀RỌ̀ NÁÀ

**2 Kọ́ríntì 9:8** Ọlọ́run sì lè mú kí gbogbo ore-ọ̀fẹ́ ma bísi i fún nyín; kí ẹ̀nyin, tí ó ní ànító ohun gbogbo nígbàgbogbo, lè ma pọ̀ si i ní iṣẹ́ rere gbogbo:

**Jeremíàh 29:11** Nítorí èmi mọ̀ ìrò tí mo rò sí nyín, li Olúwa wí, àní ìrò àláfíà, kì sí íṣe fún íbi, láti fún nyin ní ìgbà ìkẹ́yìn àti ìrètí.

**Fílíppì 4:19** Ṣùgbọ́n Ọlọ́run mi yóò pèsè ní kíkún fún gbogbo àìní nyín, gẹ́gẹ́ bí ọrọ̀ rẹ̀ nínú ògo nínú Krístì Jésù.

**Rómù 15:13** Njẹ́ kí Ọlọ́run irètí kí ó fi gbogbo ayọ̀ òn àláfíà kun nyín ní gbígbàgbọ́, kí ẹ̀nyin kí ó lè pọ̀ ní irètí nípa agbára Ẹ̀mí Mímọ́.

**Orin Dáfídì 16:11** Ìwọ ó fi ipa ọnà ìyè hàn mí; ní iwájú rẹ li ẹ̀kún ayọ̀ wà: lí ọwọ́ ọ̀tún rẹ ni dídùn-inú wà láíláí.

**Orin Dáfídì 126:5** Àwọn tí nfi omijé fun ìrúgbìn yóò fi ayọ̀ ka.
**Orin Dáfídì 118:24** Èyí lí ọjọ́ tí Olúwa dá: àwa ó ma yọ̀, inú wa yóò sì ma dùn nínú rẹ̀.